**ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU**

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**ÈTÒ ÌPÀDÉ AGBÁRA GBỌ́DỌ̀ PÀRỌ̀ ỌWỌ́**

**ṢE OHUN TUNTUN NÍNÚ AYÉ MI**

**OSÙ KẸJỌ, ỌDÚN 2021**

Ìwé Mímọ́ kíkà: Jòhánnù 1

Ìjẹ́wọ́: Ìsáíàh 49:19

**ORIN ÌYÌN ÀTI ÌJỌ́SÌN TÍ Ó L'ÁGBÁRA**

1. Ọlọ́run, dìde, kí Ó sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìṣọ́ji, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, jẹ́ kí agbára àláfíà àti itẹ̀síwájú, ṣíji bo orílẹ̀-èdè yìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fún wa ní àwọn olórí tó bẹ̀rù Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
5. Ọlọ́run ìbẹ̀rẹ̀ ọ̀tun, dìde nítorí mi, ní orúkọ Jésù.
6. Ayọ̀ ọ̀tun, ọ̀pọ̀ Ìjẹ́rì ọ̀tun, dìde, ṣàwárí mi nípa iná, ní orúkọ Jésù.
7. Ọlọ́run dìde, jẹ́wọ́ orúkọ Rẹ nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
8. Ọ̀run lórí àwọn àlàjá mi, ṣí nípa iná, ní orúkọ Jésù.
9. Ọlọ́run tó ndé lójijì, dìde nípa àrá agbára Rẹ, Ṣe ohun tuntun nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
10. Gbogbo ilé ìkẹ́rù sí àti ilé ìfowópamọ́ si òkùnkùn tó gba àwọn ẹ̀rí mi dání, fọ́, kí o sì tú àwọn àlàjá mi sílẹ̀, ní orúkọ Jésù.
11. Afi àwọn ànfàní ṣòfò, ṣòfò nípa iná, ní orúkọ Jésù.
12. Ọlọ́run, dìde, yí àwọn òfin padà nítorí mi, ní orúkọ Jésù.
13. Ọlọ́run Jákọ́bù, farahàn lókè àkàsọ̀ mi, ní orúkọ Jésù.
14. Ẹ̀yin ángẹ́lì ohun tuntun, ẹ bẹ èmi àti ìdílé mi wò, ní orúkọ Jésù.
15. Olúwa, gbin àwọn ohun tuntun sínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
16. Olúwa, fa gbogbo ohun búburú tu kúrò nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
17. Gbogbo ìkùnà nínú ètò ìṣúná owó nínú ayé mi, gba ìfòpinsí báyìí, ní orúkọ Jésù.
18. Gbogbo àìsàn nínú ayé mi, gba ìfòpinsí báyìí, ní orúkọ Jésù.
19. Gbogbo àwọn olùfà ìṣòro, gba ìfòpinsí báyìí, ní orúkọ Jésù.
20. Mo ya gbogbo ìkokò tẹ̀mí tó n ṣiṣẹ́ lòdì sí ayé mi lárọ, ní orúkọ Jésù.
21. Ohun tó n dènà dídi ẹni nlá mi, bẹ̀rẹ̀ siní kúrò lójú ọ̀nà mi báyìí, ní orúkọ Jésù.
22. Gbogbo àlùmọ́nì mi tó wà nínú túbú tàbí èyi tí wọ́n ti gbé sin, bẹ̀rẹ̀ síní bú jáde báyìí, ní orúkọ Jésù.
23. Ẹ̀yin olùrànlọ́wọ́ tíkò báni dọ́rẹ, mo pàṣẹ fún yín lórúkọ Jésù pé, ẹ kúrò lọ́dọ̀ mi, ní orúkọ Jésù.
24. Gbogbo ìdókówò tó lòdì, tó n yọ ayé mi lẹ́nu lọ́wọ́lọ́wọ́ lọ́nà òdì, gba ìfagilé, ní orúkọ Jésù.
25. Mo pàṣẹ kí gbogbo àwọn iṣẹ́ òkùnkùn tí wọ́n ṣe lòdì sí ayé mi níkọ̀kọ̀, kí wọ́n tú sí gbangba, kí wọ́n sì tún di asán, ní orúkọ Jésù.
26. Olúwa, bí ayé mi bá kọrí sójú ọ̀nà tíkò tọ́, Ẹ ṣàtúnse mi, ní orúkọ Jésù.

27. Gbogbo pẹpẹ tó lòdì sí itẹ̀sìwájú tí wọ́n ṣe lòdì símì, gba ìparun nípa àrá iná Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
28. Mo pàṣẹ kí àyànmọ́ mi yípadà sí èyi tó dára jùlọ, ní orúkọ Jésù.
29. Ọwọ́ mi, di idà iná láti gé gbogbo igi òkùnkùn lulẹ̀, ní orúkọ Jésù.
30. Gbogbo agbára tó n fọ́nu tí wọ́n yàn lòdì símì, gba ìpalẹ́numọ́ títí laí, ní orúkọ Jésù.
31. Mo gba gbogbo ànfàní mi kúrò lọ́wọ́ àwọn aninilára, ní orúkọ Jésù.
32. Gbogbo àmì tíkò lérè nínú ayé mi, parẹ́, ní orúkọ Jésù.
33. Gbogbo agbára tó n lé àwọn ìbùkún mi jìnà, gba ìyarọ, ní orúkọ Jésù.
34. Gbogbo ohun rere tí àwọn ọ̀tá ti jẹ tán, ẹ pọ̀ wọ́n báyìí, ní orúkọ Jésù.
35. Ifòròróyán fún alàjá tẹ̀mí, bàlé mi, ní orúkọ Jésù.
36. Olúwa, sọ mí di ẹni tí adúrà ti di bárakú fún, ní orúkọ Jésù.
37. Olúwa, fi iná Rẹ ran ìgbé ayé àdúrà mi, ní orúkọ Jésù.
38. Olúwa, ró pẹpẹ àdúrà mi lágbára lọ́tun, ní orúkọ Jésù.
39. Olúwa, fún mi lágbára láti borí gbogbo ìdíwọ́ sí àwọn àlàja mi, ní orúkọ Jésù.
40. Olúwa, fún mi ní ìtọnà atòkèwá láti bọ́ kúrò nínú àwọn iṣòro mi, ní orúkọ Jésù.